Ogun Ita'ja

E Polowo oja yin sinu Iwe Irohin Eleti-Ofe, Kia L'oja o ta.

ELETI OFE
A-NJU-WON KO SE WI L'EJO

Akiyesi Pataki

A fiwe yi şe ikede si awọn Aşoju iwe irohin Eleti Ọfẹ kakiri agbaiye wipe, ẹnikẹni ti ko ba fi owo ti o ti jẹ ranşẹ si wa ,ao pe lẹjọ, ako si ni fi iwe rohin ranşẹ si ẹnibẹ mọ.

VOL. XI No. 612. LAGOS, SATURDAY, FEBRUARY 21 — FEB. 27, 1959 KỌBỌ MEJI (2d).

# Alufa Ijebu-Ode To Pe Arare Ni Madi D'ologbe

IJEBU-ODE Ọkunrin kan ti nwọn npe ni Mahdi ni Ijẹbu-Ode ti o wasu kakiri Eko ni ọdun 1940 ti o si sọ asọtẹlẹ nipa buburu ti yio şẹlẹ ninu ogun ti o nja lasiko na, ni a gbo wipe, o lo si ilu Ghana lati lọ wo ara rẹ san, ọhun lo si ku si.

Alufa nla ni a mọ Shehu Mahdi Ijebu-Ode yi si, o si tun ni mimọ pẹlu, ọmọ kewu re pọ si o lowo low o pẹlu. Şugbon iyalẹnu lo je fun gbogbo awon Alufa lati gbo wipe, Alufa Ijẹbu na, gẹgẹbi oruko ti a mo o, pe ara rẹ ni Mahdi.

Lasiko ti Mahdi Ijẹbu-Ode yi dide to di ẹniti a w ọ n Saabe (ọmọlẹhin) rẹ po jaburata, nigbati o nlọsi Mẹka ninu odun 1942, ogunlọgọ awọn enia l'o ko lọ si Mẹka ti ọpọlọpo nwọn ko si pada wa sile mo titi di oni yi.

Latigba ti Mahdi Ijebu-Ode ti pada bọ lati Mẹka ni nkan ko rọgbọ fun mọ, ti okiki rẹ si ti nrẹlẹ ti ẹnikan ko si gbụro rẹ mọ lati odun 1948.

## Iyan Omi Da Ijaiya Sile Ni Accra

GHANA. A gbọ irohin wipe ọrọ ọda omi ti o şẹlẹ nilu Accra ti o di ohun ti awọn enia ko fi ri omi mu gẹgẹbi n w ọ n ti fẹ da ijaiya silẹ, gbogbo enia lo si nke orugbẹ omi kaka ti ọrọ na iba fi san, o tunbọ mburu siwaju ni.

Gẹrẹ ti a gbọ irohin yi tan ni a gbọ wipe ọkunrin ọjọgbọn kan tun şeşẹ de lati ilu Amẹrika ti o mọ aşiri pupọ nipa odo lati wa tun omi Accra şe.

Alejo na pe awọn oniwe irohin jọ o ni ki nwọn sọ fun gbogbo enia wipe, ko nşe ilu Accra nikan ni ọda omi kọkọ şẹlẹ bẹni o nşe nibi gbogbo bakanna bi awọn ti nşe ti ilu yoku ni awọn yio şe ti Accra pẹlu.

## Ejo Awon Ti O Nse Owo Eru

WARRI. Awọn enia mẹfa kan ni ọlọpa ramu fun ẹsun wipe nwọn nşe owoẹru (Slave Trade) orukọ awọn enia na ni wọnyi : Akpan Willie Udo Ekpo, Jackson Udo, Etim Akpan Jacobs Solomon ati Michael Ebongo, awọn enia nwọnyi wa lati ilẹ Kalaba si agbegbe ilẹ Shekiri lati ma wa şe owo ẹru.

Nwọn ji awọn ọmọ mẹrin gbe nilẹ Warri nwọn si ko wọn sinu ọkọ lọ ta fun awọn Ijọ. Ọkunrin kan ti nwọn npe ni Jack Etentuk ti o n ş e akapo f u n awọn ọkunrin ti o nşowo ẹru wọnyi, nigbati nwọn ramu, o tete yara ko £262 owo awọn ẹru ti nwọn ti nta.

Nigbati adajọ ri oye pe ẹjọ na ko nşe eyiti a le fi oju kekere wo, o yẹ ẹjọ na si ọjọ Monday 2nd oşu March 1959.

## OMO EGBE SCOUTS NLO SI AUSTRALIA



Ni odun 1960, ilu New Zealand 'ni awon Scouts yio şe odun Jamboree won. Ẹniti a nwo ninu aworan yi je omo Gẹşi kan ti o nlo tẹlẹ siwaju de awon ẹgbẹ Boy Scouts ni Autralia.

Ohun pataki ti a gbo pe omo na fẹ lo şe ni wipe o fẹ şiwaju won de ibẹ ki o le mo orişirişi ona abuja ti yio mu awon e g b ẹ re rin nigbati n w o n ba de.

## Awe Mbo, Oko Imale

Gbogbo awọn igbimo janma Musuluni fi ohun so kan wipe ni ojo 11th oşu March ti ao bo si yi, ni awon ... Imale jake-jado gbogbo aiye yio bere awẹ ogbon ojo nwon o kirun asamu ni ojo Atalata 10th osu March awe na yio pari ni ojo 9th oşu April, ao kirun o d u n kekerein ojo 10th April (Idul Fitri)

Irun odun Ileya (Eidel duaya) yio bo si ojo 16th osu June 1959. Ọjo i b i A n o b i Muhamed, eyi ti nwon npe ni Nobiyu Lawani yio bo si ojo Monday 14th o s u September 1959.

## Omo Akeko Kan To Yege Gbayi



Ọkan ninu awọn ọmọ Akẹko ti o lo kọ iṣẹ nilu Oyinbo, ni a nwo ninu aworan yi nigbati o nṣe awuye-wuye fun yiyege ti o yege ninu ẹkọ rẹ, ọmọde kan gbe ododo lo fi yẹ si.

## Toripe Adamu Wa Nile, Kama Gbodo Se Hun

OKUN- AJA. Ọmọbinrin kan mbẹ ni Okun Aja ti orukọ re nje Sariyu, o jẹ obinrin ti muna gidigidi, Iyalode kan lo si jẹ ninu Awo Ọpa. Gbogbo enia a si ma sa fun laifi rẹ ko si ẹniti ko le pe ni ẹjọ si kotu Ẹpẹ, nitoripe o jẹ ẹniti o lowo lọwọ jọjọ.

Bi enia fi oju sọrọ, o gbọ ohun ti o wi, bi enia fi ọwọ tabi ẹsẹ sọrọ, o gbọ, ṣugbọn bi enia bu u, tabi o bu baba rẹ, ko ni dun wọra, ṣugbọn bi enia ba bu iya rẹ, ko kọ lati fi ori sọlẹ.

Sariju jẹ obinrin kan ti o le gbo ẹjọ, alebu kan si mbẹ lara iya rẹ ti ko s ẹniti o gbọdọ fi bu u alebu na ni pe igimu iya rẹ ti ge. Sariju a ma finran nigba-gbogbo nitoripe ko si ẹniti o gbọdọ lanu ori rẹ fi bu u.

Ẹnikan le ẹlẹdẹ lati ode wọle, gbogbo enia si nwi pe Ha! ẹlẹdẹ, tabi ẹṣẹ iwọ ti o fi udun hun hun' hun bi ẹlẹdẹ. Ọrọ yi bi Sariyu ninu, o si lọ pe ẹjọ ni Ẹpẹ. Adajọ dahun pe Kini ! a ha le titori adamu wa nile ki a ma gbọdọ daruko ṣe hun ?

## E fi Ola Fun Eniti Ola Nse Tire

Lati Ọwọ Ẹṣọ

Gbogbo ọla omi to mbẹ laiye ko le pọ ki o to ti Olokun, Gbogbo odo ti o ṣe lati Oke Oyi ko le pọ ki o to ti Ọlọsa, Adifa fun Ọbatala, Ọṣẹrẹ-igbo Lọjọ ti yio joye Alaba Ti Odumare yio jẹ Alaṣẹ. Eji-Ogbe

Ni ọjọ kan Olodumare sun ilẹ na, gbogbo wọn lo sibẹ a yafi Ọbatala nikan ṣoṣo lo tu ibẹ na. Nigbana ni Olodumare wa fi Ọbatala joye Alaba, Olodumarẹ Papa si fi ara rẹ joye Alaṣẹ. Lati ọjọ na wa, bi Ọbatala ba ya ẹda enia kan gẹgẹbi o ti wu u, Olodumare a si ṣe aṣẹ si.

Lẹhin ti Ọbatala joye tan ni inu wa bẹrẹ si bi awọn Irunmọlẹ yoku wipe, Họwu, bawo ni ẹnikan tiṣe le joye gbogbo to mbẹ lọrun tan awọn yio nura ki awọn le gba diẹ jẹ ninu awọn oye ti Olodumare fifun Obatala jẹ Orunmila, nigbati o gbọ idi ọrọ yi, o yọ ara rẹ kuro larin wọn wipe, rara on ko lọwọ ninu rẹ. Nigbati Ọrunmila yehun, Ẹlẹgbẹra pelu yẹhin.

Ejiogbe ti o dibo yan Obatala si oye na, lati ọjọ na wa gbogbo awon o gbẹ gbẹrugbẹru. Odu ifa na tun wi bayi siwaju wipe.

Mo tọrọ ọla lọwọ Olokun jẹki-nade

Mo ri jẹ, ṣungbọn nko yo

Mo tọrọ lọwọ Ọlọsa Mo ri je

ṣugbọn nko yo Tani ko mọ

pe Ọla Ọlọrun lo to gbojule.

Eijogbe

## AWỌN ALAPATA FẸ KỌ ẸRAN PIPA SILẸ

EKO. Awọn Alapata Eko ati awọn ti o nṣe owo eran Malu ni edẹ koyede bẹ silẹ larin ara wọn larapa a tunijẹ, a ko tunijẹ, tobẹ ti ẹgbẹ awon Alapata fi pinnu pe ko ni pa eran.

Ọgbẹni Ojikutu ti o nṣe baba ẹgbe awọn Alapata sọ pe, awọn Onila-ada ti ojẹ Alarena larin awọn Alapata ati Onisowo ẹran malu lo da edekoyede na silẹ, bi nwọn ko ba yowọ ti wọn kuro, awọn alapata ko ni pẹran, nitoripe ko si eyiti o kan wọn nibẹ. O yẹ ki olukuluku ran ti ara rẹ.

Iba iṣe wọn nipe, bi alapata ba ra malu kan fun pipa, ki nwọn gba ṣile mẹwa lori malu kan na. Ṣugbọn awọn Onila-ada nwọnyi ṣe gegere lori gegere, bi malu ba de, nwọn o ra malu fun wọn, nwọn o si ma fun ta ni owo geregere.

Ọgbeni Ojikutu sọ pe, laijẹ wipe, olukuluku mọ iṣẹ rẹ nisẹ rẹ nise, aijọse awọn ko le rọgbọ. Awọn Alapata ko ni pa ẹran titi ọro na yio fi yanju.

# Eto Fun Awon Ti Nlo Si Mecca

## Lati Ipinle Iwo Orun

Ninu ikede ti a kọko tẹ sinu iwe yi, a pe awọn ti nlọ si Mecca ati Mẹdina ninu ọdun yi ki nwọn kọ iwe si Akọ'we Igbimọ ti nṣe eto fun awọn ero titi ọjọ kẹdogun Oṣu yi.

Igbimọ si ti pinnu nisisiyi lati gba irufẹ iwe bayi titi di ọjọ kejidilọgbọn Oṣu yi.




## ORIKI BAMWO

Bamwo de, alajẹla ọmọde agbọmola bi orişa, akọ ọlukọ ogun ti ndamọ l'ẹkun igbona, atata ogun ti npa o tutu rẹ warawara a jẹ bi idan, a gba bi ẹtu ibọn. O s'abiku di ikugbagbe, o ş'ọmọ ti nhehin l'ore. Ikọ ri i sa, Iba ko l'ọna tagiri, aiperi ri d'ẹkun iyọnu Olugbala f'ọmọ ti nyagbẹ orin o kapa inu wọ, o lu jẹdi l'alupa gbogbo abiyamọ nyọ ṣẹṣẹ. Ela ri i o roju, Ọrẹrẹ ri i o na'gbẹ bo'ra Ẹyi npa lẹmọ lodilẹsọ, ọrẹ ikoko, koşemani awọn abiyamọ, ẹni araiye njijadu ra. O de ilu Ibo, o dọga o de ilẹ Hausa, o d'ọba gbogbo Onişegun l'o sọ pe ko lẹgbẹ gbogbo ọmọdẹ lo nfẹ ẹ fun ilera.

IGO KEKERE 2/6d IGO NLA 4s owo ọkọ lọtọ.

THE ẸGBA TRADING
ARADAN STORES

18, Denton Bridge Street.
P. O. Box 2 Ebute -Meta

## Itan Elegbeje-Ado

Lati ọwọ Y. ADE BURAIMỌH

ỌMỌ OTUN-ORO

**Iṣẹgun ti mo ṣegun awọn ọlọṣa ki iṣe agbara mi, bikoṣe agbara yin ati agbara Edumare ati awọn Iya mi Oṣoronga to ran mi lọwọ lati hori awọn Janduku enia ti ko jẹki ọmọde ati alagba sinmi ni ilu yi, ipari ọrọ mi siyin loni yi nipe ki Ọlọrun to laiye ati Ọrun ran yin lọwọ kio si pẹlu emi na papa ninu ohunkohun ti mo ba da ọwọ le titi emi yio fi ṣẹgun awọn Alijannu buruku to wa ninu awọn igbo ọsundundun to wa li ẹgbẹ ilu wa yi, ni agbara yin, emi yio lọ gbe ogun ti Ẹbọra Ọsundundun to wa ninu igbo Ọsundundun, ti ẹ b pẹlu mi, emi yio ṣẹgun ẹo si tun ma gbọ irohin bakanna ni agbara Edumare.**

ODẸ ELEGBEJE ADO MURA LATI MA LO SI IGBO OṢUNDUNDUN

**Ọdẹ Elegbeje Ado dagbere fun awọn ara rẹ pẹlu awọn alabagbe ile rẹ bakanna lo sọ fun awọn ojulumọ rẹ kio to jade ni ile o fi odu kan si awọn ara ile rẹ leti bayi pe Tẹtẹ ki itẹ lawujọ ẹfọ Edumare maje ki ntẹ larin awọn Alujọnu, ki ewe oko ṣetemi ki igi oko ṣetemi Olugbo igbo ṣe temi. Iroko igbo ṣe temi, Ọpọtọ igbo ṣetemi ẹnyin Iyami Oṣoronga ẹ tẹlemi, akaṣum gba ki igbọọ ẹkun ọmọ rẹ ko duro Abiyamọ ki igbọ ẹkun ọmọ rẹ ko ma dide ore ni igun ṣe ẹranko ẹgbẹ rẹ lo pa lori ẹ ma jẹ ki temi ri bẹ. Arọni ni ogun titi iku ejo loku, ki temi ma jẹbẹ Edumare.** Bi o ti sọ Eyi tan ni o ba di m ora di mọra gẹgebi jagunjao jade kuro ni ile o ni ki awọn ara ile ma gbagbe on ti mo ba ku si ọhun, tori iku ogun lo npa akinkanju, iku odo lo npa omuwẹ iku owu riran lo npa alantakun sinu ile, ire ni ki temi jasi Edumare.

ODẸ ELEGBEJE ADO DE ẸSE IGBO ỌSUNDUNDUN

Elegbejo-Ado de ẹsẹ igbo Ọgẹdẹ o kọkọ pe nipe Olu igbo mojuba gbogbo yin igi igbo mojuba gbogbo yin ewe igbo mojuba gbogbo yin ẹda igbo ẹba mi da ẹbọra ẹbọra ọṣundunẹfi igbo ẹba mi fi ẹbọra Ọṣudun lakalaka de ajule ọrun ha Edumare ẹnyin Iya mi Oṣoronga ẹ pẹlu mi aja ki igbagbe olore ẹkọ Aguntan ki igba gbe eleri bọrọ-bọrọ, oma gbagbe mi Gbogbo ohun ti mo ba ṣe ki ẹ fi ori jinmi ki ẹ maṣe binu simi toripe Ojo ki iku ko gbagbe Ara bẹ sini ẹsẹ ki i ba ọna ja rara toto ose bi owe o.

(Koït Pari)

E MA KA IWE IROHIN ELETI - OFE L'ỌSỌSẸ OKUN FUN IROHIN ALADUN



# ELETI - OFE

A-NJU-WỌN KO ṢE WI L'ẸJỌ

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAM

28, Kosoko Street, Lagos. "ELETI - ỌFẸ LAGOS"

P. O Box 467 Phone 23370

VOL. XI. NO. 612. SATURDAY FEB. 21 - FEB. 27, 1959


## Oku Ojo Mejo Pere !

Ni ọjọ mẹjọ oni ni asiko if'orukọ silẹ fun idibo ni ilu Eko yio pari. Nitorina, ki ẹnikẹni ti o ba ti to ọmọ ọdun mọkanlelogun ti o si ni ẹtọ ati dibo maṣe jafara lati lọ fi orukọ silẹ nitoripe ibo ti a o di lotẹyi, nilu Eko nilu Oke ati ni Oke - Ọya jẹ pataki julọ ti a o fi yan awọn enia ti yio mu opo ijọba wa dani nigbati a ba gba ominira ilẹ Nigeria eyiti ao gba ni ọjọ kini oṣu October ni ọdun ti o mbọ (1960), lagbara Edumare.

Bakanna ni a kesi awọn enia wa ni lu oke, ni ipinlẹ Iwọ - orun wipe ki nwọn maṣe jafara lati fi orukọ silẹ fun idibo na nitoripe eyi ni yio jẹ idibo pataki julọ ti ao fi yan awọn enia pataki ti yio jẹ opo-mulero ijọba ilẹ Nigeria wa nigbati ba gba ominira, ati paapa gẹgẹbi a ti gbọ wipe orukọ ti awọn enia ba fi silẹ fun idibo ile igbimọ nla ti ilẹ Nigeria yi (House of Representatives) ni yio wa fun lilo fun gbogbo ibo ti ao ba tun di fun awọn ile igbimọ Aṣofin ati igbimọ ibilẹ ni ipinlẹ Iwọ-orun. Bi enia ko ba fi orukọ silẹ ko ni le dibo, iba ṣe ti ile igbimọ nla tabi ile igbimọ kekeke ti a mọ gẹgẹbi igbimọ ibilẹ. Ifi orukọ sile na yio pari ni ọjọ kẹrinla oṣu March 1959 ni ipinlẹ Iwọ-orun. Nitorina ẹ ma jafara, ijafara lo lewu.


## Imoran Fun Enyin Abiyamo

Enyin Abiyamọ ẹ wa ra ỌMỌRẸLA o dara pupọ fun awọn ọmọde.

Ama fẹ ki ọmọde ri orun sun daradara o dara fun otutu, ikọ ati orişirişi arun miran ti o ma mba ọmọ ja ni asiko ehin. Ọpọlọpọ abiyamọ lo ti lo egbogi yi fun ọmọ wọn ti won si sọ wipe o dara pupọ fun awọn ọmọde

ỌMỌRẸLA BABY MIXTURE

(Şile Meji Abọ 2/6d Fun Igo Kan)

O wa Lọdọ

COMMERCIAL MEDICINE STORES
(Qualified Chemists)

10, VICTORIA STREET, LAGOS.


## ỌLỌRUN ŞE ẸDA ENIA JU GBOGBO ẸDA YOKU LỌ

O bere ninu Iwe wa ose to koja

kini lagbara ju ẹfufu lo ? Olodumare dahun pe o wa, nwọn ni kini Olodumare sọ fun won pe enia lagbara ju ẹfufu lo. Nwon tun bere pe kini ohun ti ti o lagbara ju enia na lo ? Nigbana ni Olodumare wi fun won pe ko si ayafi On Ọlọrun nikanşoşo lo ju enia lo.

Nitorina, ibẹru bojo irohin ti nwọn ti gbọ yi ko jẹ ki nwọn le sunmọ Afin Ọla nigbati Olodumare nşe ẹda enia, nse ni nwọn takete nitoripe, bi Ọlọrun ba se ẹda rẹ pari tan ki o ma ba fa wọn ya pẹrẹ-pẹrẹ. Ati nigbati Ọlọrun pari ẹda enia tan Ori enia na lo kọko fi ọpẹ fun Ọlọrun fun didu ti o da on.

Ogede-gede wipe o sọrọ, nşe ni gbogbo awọn Irumọlẹ nwọnyi nsalọ, nwọn tadi mọ okere nwọn nwo, Ori tun sọrọ pe, mo ki nyin o, ẹnyin ẹda iṣẹ ọwọ Ọlọrun, itiju mu wọn nitori nwọn ko mọ bi nwọn o tişe dahun tabi esi ti nwọn o fun.

## Anu Ijoba Ila-Orun Senia

ABA. Ọgbẹni S. O. Achara ti o jẹ Sẹkitẹri ẹgbẹ Dẹmọ lo sọrọ yi wipe, larin ọdun 1954-1958 ninu eyiti N.C.N.C. fi şe ijọba Ila-orun, ko si gbadun kan larin ọdun na, ọdun marun na jẹ ọdun ibanujẹ ati egbe.

Bi ẹnikan ba nsọ wipe ijọba Ila- run ko le duro bi ko si ọwọ Asikiwe ni bẹ, o daju pe ẹsẹ ni oluwarẹ gba lọ sọdọ Ọlọrun.

Ẹgbẹ Dẹmọ ko si fun darudapọ, bikoşe fun otitọ ati ododo nibi gbogbo.

O fi ye gbogbo enia wipe ominira ti o mbọ yi, patapata ni ao gba ominira na, nitorina ki gbogbo enia dibo fun ẹgbẹ ti wa, şugbọn ẹnikẹni ti o ba dibo fun N.P.C. awọn Hausa, ki oluwarẹ mọ pe, on ndibo fun Ọgọrun Bulala, bi o ba si dibo fun N.C.N.C. oluwarẹ ugbẹ koto ararẹ, nitoripe patapata adiẹ akukọ ko le gba tayọ ọdunmẹta. Ẹdibo fun wa.


## Onisowo Ohun Isere Omode

### Coopexim

COOPERATIVE COMPANY FOR FOREIGN TRADE LTD.

WARSZAWA, ZURAWIA 4, POLAND.

TELEGRAMS : COPEX - WARSZAWA.

Ohun ti a nta niwọnyi :- Bebi (Dolls) ati awọn ohun işere ọmọde, Adamọdi igi-ọdun Keresimesi, awọn ohun ọṣọ-ara ati ọṣọ-ile, Orişirişi Brọşi (Brushware) Orişirişi ohun ipẹja, Şuku ati Apẹrẹ lorişirişi, awọn nkan ti a fi irin şe, Orişirişi awọn ohun ti a fi nya aworan, Orişirişi aşọ ẹwu t'ọkunrin t'obinrin awọn nkan ti a nko ẹfọ ati eso pamọsi, Egbogi mimu ati pipara, Aşọ Bulankiti ati Damasi.

A NFẸ AŞOJU NIBIGBOGBO

## Oloye Akintola Fo Soke O Bejo Lori



Oloye S. L. Akintọla so pe, o ye ki gbogbo aw 'ṣẹtanti wipe igbimo pupo lo mbẹ fun ẹgbẹ Alakuko ti nwon nilatiṣe amojuto igbimo, ko niye igba ti Ijoba nda igbimo won ru.

Owe kan wipe, ẹniti yio fun ni lẹwu wo a ni lati koko wo ti orun rẹ na, ẹ wo Asikiwe to wipe on yio ṣe itoju igbimo ilu Eko kiloti ṣe ijoba ilu tire paapa ṣi? Nigbati nwon nṣe ijoba ibile Eko, ko ha nṣe dida ru ni nwon da igbimo na ru gbẹhin. Nitorina, ẹ dibo fun ẹgbẹ olope, ki ire ,na le kari wa.

## ITAN AJAPA ATI EKUN

### APA XIII

Lati owo Ẹṣo

Nisisiyi ti Ajapa ri ehin Ẹkun, ọmọ Ẹkun wa bẹrẹ si lepa Ajapa kakiri, ṣugbọn oju Ajapa muna, ki ọmọ Ẹkun to ri ajapa, ajapa ti rii, o si ti fi ara ṣoko. Agbẹ kan ṣe ofofo fun ajapa wipe, ki o lọ sọ ara rẹ, nitoripe ọmọ ẹkun nlepa rẹ kiri Ajapa dahun pe hẹ, ṣe ọmọ ẹkun sa fi eleyini silẹ ọmọde lo nṣee. Jẹki nsọ fun ọ, iwọ agbẹ bi o ba jẹ wipe, ẹniti o ba kọkọ ri ni lo nmu ni lẹru, awọn ẹru mi ibati pọ nitoripe, nigbara ti Oloko ti de oko ni mo ti ri. Iwọ ṣa fi ọmọ ẹkun silẹ, ki o to fa mi lori ngo fa a lori.

Bi Ajapa ti kuro nibẹ o wọle tọ ọba lọ o ko ifa rẹ o da silẹ niwaju ọba, o si ri Idajo, oni ha oba fẹ jẹ igbẹ ọba tagiri o kigbe wipe on Ọba fe jẹ igbẹ tabi kinla : Ajapa sọ pe Kabiyesi ọba ifa ko npurọ. Ọba dahun pe abuku ni ọrọ rẹ yi jẹ leti mi, bi o ba jẹ enia lasan kan lo sọ iru ọrọ ti iwọ Ajapa s yi, ngo jẹ ni iya. Ṣugbọn ngo fi eyi mọ otitọ ọrọ rẹ. Ajapa so pe lati ọjọ ti on pẹlu ọba t nṣe ilu pọ on ko purọ fun ọba ri njẹ bi ọrọ ifa yi ba jẹ ododo kini ọba yio se fun mi. Ọba woye lọ titi wipe bawo ni on yio ṣe laju sile ti on yio rigbẹ ti on yio si bẹre si ko jẹ

Ọba ṣeleri wipe bi ọrọ na ba jẹ be nibi gbogbo ti on ba gunwa si Ajapa yio ma joko lọwọ ọtun on ohunkohun ti Ajapa ba si bere ni ao ṣe fun u. Egberegbe, egberegbe, o to iwọn ọdun mẹta lehinna.

Igi iroko kan mbẹ ni ẹhinkule ọba ti o ti ku bi iwọn ọgbọn ọdun sẹhin. Ajapa lo ko igbẹ lie ti o ti gbẹ jọ o lọ ọ di lubulubu o fi oyin po, o ṣu rodo-rodo o wa gun ori igi iroko na lọ ni oru o fi rodorodo gun ori awọn ẹka igi kọkan o wa da iyoku silẹ.

Nigbati ọkan ninu awọn ẹru ọba nlọ si oko lati lo ka ila, o de ibiti iroko yi gbe wa, ti o si ri eso nilẹ jingbinni, o wipe ha! aṣe iroko yi koiti ku o bẹrẹ o mu eso kan o to wo, o ri pe o dun o tun bẹre nigbati o ma jẹ bi won ogun lo ba te idiku sile o dii o gberu o di ọdo oba

O ni Kabiyesi, Ohun ti mo ri loni yanilenu jojo, iroko rẹ ti o ti ku lati oio pipe wa so jingbinni eso re na niyi ki ọba towo bi o ti dun to.

Nigbati oba towo ti o si dun ko mo igbati o jẹ gbogbo rẹ tan, o ni ki nwon gbe aga on niṣo nibiti iroko na gbe wa, bẹni ọba bẹrẹ si jẹ.

Lọṣẹ to mbo ao sipaiya bi oba ti ṣe mo pe igbe ni on jẹ ati bi Ajapa ti ṣe gba iyi na ẹ ma ka iwe irohin Eleti-Ọfẹ

**E MA KA IWE IROHIN ELETI - OFE**
**L'ỌSỌSẸ OKUN FUN IROHIN ALADUN**


# NISISIYI !

FUN IGBA AKOKO NILE NIGERIA...

AWỌN ONIṢOWO

**THE NIGERIAN GAS CORPORATION LTD**

YIO MA ṢE

ETO OHUN IDANA GAS SINU ILE LATI MAFI DANA

Ale fi Gas pẹlu Meter rẹ sinu ile ti a ngbe Koni agbekiri. Ko si ni ṣalai muna wa nigba kan. Ko lewu, o rọrun, lilo rẹ din inawo ku.

ẸNYIN KỌLEKỌLE, ONILE ATI ẸNIKẸNI TI Ó BA FẸ LILO RẸ KI O KỌWE FUN ALAYE KIKUN LỌDỌ :-

**NIGERIAN GAS CORPORATION LTD.**

2, ITAPEJU AVENUE, P.M. BAG 1040 APAPA TELPHONE 55295,

Iye owo rẹ ati gbogbo alaye nipa rẹ ni ao ṣe fun yin lọfẹ.

# Electricity Corporation Of Nigeria

## Invitation To Tender

**SAPELE—WARRI 33 K.V. TRANSMISSION LINE**

Tenders are invited from responsible Contractors for the survey, design, supply and erection of a 33,000 Volts Single Circuit Transmission Line between Sapele and Warri.

Tender documents comprising Tender, Form of Contract, Specification of the Contract, etc., may be obtained on payment of a deposit of £5 from :

The Secretary,
Electricity Corporation of Nigeria,
Electricity Headquarters,
Private Mail Bag 2030,
Broad Street, Lagos.

Each tender must be enclosed in a sealed envelope endorsed "Confidential Tender for Sapele - Warri 33kv Line" and must be received at the Office of the Secretary not later than noon 7th March 1959. Tenders received in any other manner will not be considered.

It is essential that the Tendering Contractor shall be in a position to produce evidence of having sucessfully undertake previous contracts of a similar nature.

On receipt of a Bona Fide Tender, the deposit of £5 will be refunded. The Electricity Corporation of Nigeria does not undertake to acept the lowest or any tender.

Further information concerning this contract may be obtained on application to the Chief Electrical Engineer at this Headquarters.

**Arthur Faul.**
SECRETARY TO THE CORPORATION

# LAGOS TOWN COUNCIL

## TENDERS FOR UNIFORMS

TENDERS are invited for the making of approximately 1000 Khaki Uniforms, 300 Jumpers and 298 Shorts and Shirts.

The uniforms must be made to measure, and the Jumpers and shorts made in two stock sizes.

Khaki cloth will be supplied by the Council but sewing thread, buttons and lining materials must be provided by the successful tenderers. Succesful tenderers must state the quantity of cloth they require for the building of each type of uniform.

The work may be divided and allocated to more than one tenderer, and the Council does not bind itself to accept the lowest or any tender.

Tenders must be submitted in sealed envelopes marked "TENDERS FOR UNIFORMS" and addressed to the TOWN CLERK, Municipal Offices, Catholic Mission Street, Lagos and must be delivered not later than 1 p.m. on the 27th February, 1959.

**D.M.O. Akinbiyi**
TOWN CLERK.

MUNICIPAL OFFICE,
LAGOS, 18th February, 1959.




# Enia Merin Njijadu Oye Awujale

IJẸBU-ODE. Gẹgẹbi aṣa ilẹ Yoruba, bi ọba Awujalẹ ba wọ aja oṣu mẹta ni nwọn ma fi nsinku rẹ. Ṣugbọn ẹnikan lo ni lati ṣe Ọmọ - Oloku na ni yio si tun pada di ọba lẹhin eyiti o wọ aja na.

Nisisiyi enia mẹrin lo ndu oye ọba Awujale gẹgẹbi ẹtọ won, ṣugbọn gẹgẹbi aṣẹ ti Ijọba Iwọ-orun fi ranṣẹ, lati idile ọgbagba ni ki nwọn ti yan ọba.

Nigbani, ọrọ a o yan ọba, a ko yan ọba ko nṣe ohun ti o le ni Ijẹbu-Ode. Ọmọ ti ọba ba kọkọ bi sori oye tabi eyiti nwọn Ijẹbu npe ni Abidagba lo ni lati gori oye ọba lẹhin ti baba rẹ.

Ọmọba lo ni lati joye Awujalẹ, o si nilа jẹ ọmọwe, awọn Ijebu nfẹ ọba titun to ba ode toni mu.

Idile Ọgbagba ti o ndu ọba na enia mẹrin eyiti o dagbajulọ ninu wọn to ogọrin ọdun, ko si mọwe, Orukọ rẹ ni Adebanjọ. Lẹhin na ni Ọladunjoye, on na ko mọwe. Ẹnikẹta ni Ẹniafẹ on na pẹlu ko mọwe, ṣugbọn nigbati o bẹrẹ si lọ silewe alẹ, a gbọ pe o le ka A.B.D.GB. ẹnikẹrin ni Adetọna, ko si le jọba. Bi awọn idile Ọgbagba ko ba yege, idile Tunwaṣẹ tun le bọsi nitoripe ibẹ ni ọmọ ile Ẹkọ Kings College ni Eko gbe wa.

## Kere o !

Ati ni orisirisi o g u n German to ṣẹṣẹ de, fun oniruru aisan tọkunrin tobinrin. Tete wa ra tirẹ ki o to tan.

**J. A. AJAO BROTHERS**

MEDICINE STORES

7. Egerton Road Lagos




## Ọgagun Agba Ninu Oko Ogun Ile Nigeria



Ẹniti a nwo ninu aworan yi ni Ọgagun agba kan ninu oko ogun ilẹ Nigeria, ẹniti [illegible] da silẹ laipẹ yi. Ibujoko awọn Oloko ogun na (Naval Office) mbẹ ni Apapa, ibẹ na si ni ibujoko awọn Sailors.

## OBINRIN KAN BI ABAMI-OMO NILU ILORIN

**ILORIN. Obinrin Adelebọ kan ti nwọn npe ni Amọsa iyawo ọkunrin kan ti nwọn npe ni Awudu ni adugbo Pakata ni Ilọrin ni a gbọ pe, o bi abami ọmọ kan ti o lori meji, apa mẹta ati ẹsẹ mẹrin.**

**Omọ na ni ori kọkan ni ejika kọkan nisalẹ awọn aji-**ka mejeji na ọwọ kan yọ jade, ṣugbọn ọwọ ṣebele kan tun yọ jade ni ẹhin rẹ o si tun ni ẹsẹ mẹrin.

A gbọ wipe ni gẹrẹ ti nwọn bi ọrọ omọ na silẹ tan bẹ lo silẹ Ọlorun wo ṣugbọn awon ojogb n ninu Isẹgun gbe oku omo na pamo.

Amoṣa ti o bi omo abami yi ko nṣe alakobi omo okunrin lo fi ṣe akobi. Nigbati nwon mu irohin lo ba oba Alaiyeluwa Saki oba Ilorin, o dahun pe bi oju ba ri oro nṣe lo nwo o fin, nitorina, ko tọ ki on ma fi oju ri omọ na, o si lo si si Pathology Hospital nibiti nwon gbe fi oku omo abami na pamọ si ti ko si le bajẹ lailai.

## OLAJA NI F'ORI GB'OGBO

EKO. A gbọ irohin pe obinrin kan ti o njẹ Victoria Ajifo pẹlu ẹgbẹ rẹ kan nja, ti okunrin kan, oninure si bo si arin wọn lati la wọn. Paki ti Victoria gon eti onilaja o geja, o si nsalọ pẹlu eti na li ẹnu rẹ, ọpẹlọpẹ ọlọpa kan ti o mbọ lo ba wọn mu obinrin na. Ọlọpa sọ fun Adajọ pe ija ni nwọn nja lọwọ ti Victoria fi ge wọn jẹ, adajọ ni ki o lọ si ẹwọn oṣu mẹta kosi gbọdọ ge enia jẹ mọ.

No 25

# FEDERAL ELECTIONS 1959

## REGISTRATION OF ELECTORS

### WESTERN REGION

**Registration of electors will take place in Western Region between**

# February 16th -March 14th 1959

**During this period Registration Offices will be open in all Constituencies at hours to be announced on official posters.**

**YOU CANNOT VOTE UNLESS YOU REGISTER NOW**

## ỌMỌ TI GAMBARI BA BI OKUN Ni YIO RAN

Lati Ọwọ R. A. Orowole

**Nigba lailai ọkunrin kan wa ti a npe orukọ rẹ ni Ọmọjọmi, ko ni iṣẹ meji ti o nṣe ju iṣẹ ole. On nikan ni o si ngbe ile rẹ, nigbati ọkunrin yi fẹ fẹ iyawo awọn mejeji si nse iṣẹ kanna, nwon si gbọ ede ara wọn to be ti o je pe oju ni nwọn fi mba ara wọn sọro, o wa dabi owe Yoruba ti o wipe "Nwọn ba ara wọn pade Ọkọ ndifa iyawo nṣe Awo" toto fun u bi o ba jo owe o.**

**Nigbati nwọn ma bimọ, ọkunrin ni akọbi wọn. Iṣẹ jaguda yi ni baba ati iya ọmọ yi nṣe ti nwon fi ntọ ọmọ na dagba. Ọmọ yi si tun mọ iṣẹ ole yi ju awọn obi rẹ lọ.**

**Gẹgẹbi ẹnyin na ti mọ iru awọn enia bẹ ki ni ọrẹ ododo arin-oru ni nwọn saba ma nṣe iṣẹ jaguda yi. Bayi ni awọn mẹtẹta lọ si oko ole ni oru ọjọ kan, nibiti awọn nfẹ kole ni ọwọ ti ba iyawo yi ti nwọn si paa ni apaku. Ọmọ ati baba nikan lo pada sile. Ọrọ yi ko ya wọn lẹnu rara nitoripe "Ọwọ ti ada ba mo ni nka ada lẹhin-**

Iku ogun ni npa akinkanju
Iku odo ni npa omuwe
Iku obinrin ni npa ugbere,
bẹni Ohun ti a ba jẹ ni iyo ni?
ki a ma fa ọrọ gun lọ titi.
nwọn fi ọrọ yi ṣe osun ati
adin nwọn fi pa ara.

Nigbati o wa ṣe baba yi ati ọmọ rẹ tun ri agbo nla kan gbe eleyi ti Lemọmu ti ra silẹ lati pa Ileya. Loru ọjọ yi ni nwọn fi kun agbo kilẹ to mọ. Ni owurọ ọjọ keji ni iyawo Lemọmu ti bẹrẹ si kegbe ẹniti o gbe agbo lọ, o si fi ẹjọ yi han Balẹ ilu, Balẹ si ti paṣẹ lati pe gbogbo ilu jọ si Afin, lakoko yi ni baba ole yi nse ẹran agbo na lọwọ. Gbogbo ilu si ti pejọ si Afin.

ITALỌWA KU SI DẸDẸ ỌJỌ ẸLẸSIN KU ỌLA

Bayi ni Omojomi dide lati ba wọn pesẹ si Afin, kio to lo nile o paṣẹ fun ọmọ rẹ pe ki o gbe Ikoko nla lena ki o si ko gbogbo eran sinu rẹ kio ma see. Nibiti ọmọ yi ti nto ẹran sinu Ikoko o wa ku ori agbo ti ko gba isa yi, eru si mba ọmọ lati la si meji ki baba rẹ ma ba wipe o yọ jẹ ni arin, bẹni ti ọmọ yi ba lọ fi ori agbo yi silẹ laise awọn ti nwọn nwa agbo le ri.

(Kosu p ari)

## OLOYE MEJI PADE



Awọn Ogunna gbẹmgbo ilẹ Gẹsi ati ilu Amerika lo f'oju kan arawọn ninu agbala Ile funfun nilu Amerika Ọgbeni H Macmillan Olotu ijoba Gẹsi ati Ọgbeni Eisenhower Olotu ijoba tilu Amerika.

Printed & Published by The Union Printing and Publishing Company 28, Kosoko Street Lagos P. O. Box 467 Phone 23370